**8.** Lẹhinna dajudaju a o bi nyin lẽrè nipa idẹra ni ọjọ na.

ثُمَّ لَتُسْـَٔلُنَّ يَوْمَئِذٍ عَنِ ٱلنَّعِيمِ ﴿٨﴾

## *(103) Suratul - ’Asri*

سُورَةُ العَصْرِ

*Ni orukọ Ọlọhun Ajọkẹ aiye,*
*Aṣakẹ ọrun.*

بِسْمِ ٱللَّهِ ٱلرَّحْمَٰنِ ٱلرَّحِيمِ

**1.** Mo fi akoko irọlẹ (’Asri) bura.

وَٱلْعَصْرِ ﴿١﴾

**2.** Dajudaju enia mbẹ ninu òfò.

إِنَّ ٱلْإِنسَٰنَ لَفِى خُسْرٍ ﴿٢﴾

**3.** Ayafi awọn ẹniti nwọn jẹ onigbagbọ (ododo) ti nwọn si ṣe iṣẹ rere ti nwọn si ngba ara wọn niyanju ṣiṣọ ododo, nwọn si ngba awọn enia niyanju lati ni farada.

إِلَّا ٱلَّذِينَ ءَامَنُوا۟ وَعَمِلُوا۟ ٱلصَّٰلِحَٰتِ وَتَوَاصَوْا۟
بِٱلْحَقِّ وَتَوَاصَوْا۟ بِٱلصَّبْرِ ﴿٣﴾

## *(104) Suratul - Humasah*

سُورَةُ الهُمَزَةِ

*Ni orukọ Ọlọhun Ajọkẹ aiye,*
*Aṣakẹ ọrun.*

بِسْمِ ٱللَّهِ ٱلرَّحْمَٰنِ ٱلرَّحِيمِ

**1.** Egbe ki o ma ba gbogbo abuni loju ẹni (Humasah) ati abuni lẹhin.

وَيْلٌ لِّكُلِّ هُمَزَةٍ لُّمَزَةٍ ﴿١﴾

**2.** Ẹniti o ko owó jọ ti o si nka a laka-tunka.

ٱلَّذِى جَمَعَ مَالًا وَعَدَّدَهُۥ ﴿٢﴾

**3.** Ti o nro pe owo on ni yio mu on ṣe gbere laiye.

يَحْسَبُ أَنَّ مَالَهُۥٓ أَخْلَدَهُۥ ﴿٣﴾

**4.** Rara o, dajudaju a o fi sọ̀kò sinu ina Hutamatu.

كَلَّا ۖ لَيُنۢبَذَنَّ فِى ٱلْحُطَمَةِ ﴿٤﴾

**5.** Atipe kini ohun ti o le fi ina Hutamatu nã mọ ọ?

وَمَآ أَدْرَىٰكَ مَا ٱلْحُطَمَةُ ﴿٥﴾

**6.** Ina Ọlọhun ti o njo geregere ni.

نَارُ ٱللَّهِ ٱلۡمُوقَدَةُ ٦

**7.** Eyiti yio mã naga bori awọn ọkàn.

ٱلَّتِي تَطَّلِعُ عَلَى ٱلۡأَفۡـِٔدَةِ ٧

**8.** Dajudaju a o ti i mọ wọn.

إِنَّهَا عَلَيۡهِم مُّؤۡصَدَةٞ ٨

**9.** Ninu awọn opo ti a fa gùn.

فِي عَمَدٖ مُّمَدَّدَةِۭ ٩

## *(105) Suratul - Fĩli*

## سُورَةُ الفِيلِ

*Ni orukọ Ọlọhun Ajọkẹ aiye, Aşakẹ ọrun.*

بِسۡمِ ٱللَّهِ ٱلرَّحۡمَٰنِ ٱلرَّحِيمِ

**1.** Njẹ irẹ kò ri bi Oluwa rẹ ti şe pẹlu awọn ijọ elerin (Fĩli)?

أَلَمۡ تَرَ كَيۡفَ فَعَلَ رَبُّكَ بِأَصۡحَٰبِ ٱلۡفِيلِ ١

**2.** Njẹ (Oluwa) kò sọ ete wọn di ohun to kùnà?

أَلَمۡ يَجۡعَلۡ كَيۡدَهُمۡ فِي تَضۡلِيلٖ ٢

**3.** Atipe O ran awọn ẹiyẹ si wọn ni ọpọlọpọ (lọwọlọwọ).

وَأَرۡسَلَ عَلَيۡهِمۡ طَيۡرًا أَبَابِيلَ ٣

**4.** Ti nwọn ju wọn ni okò ti a sun ninu ina (Sijjili).

تَرۡمِيهِم بِحِجَارَةٖ مِّن سِجِّيلٖ ٤

**5.** O si şe wọn gẹgẹbi ẹ̀run koriko ti a (ẹran) jẹkù.

فَجَعَلَهُمۡ كَعَصۡفٖ مَّأۡكُولِۭ ٥

## *(106) Suratul - Kuraeşi*

## سُورَةُ قُرَيۡشٍ

*Ni orukọ Ọlọhun Ajọkẹ aiye, Aşakẹ ọrun.*

بِسۡمِ ٱللَّهِ ٱلرَّحۡمَٰنِ ٱلرَّحِيمِ

**1.** Nitori ibasãba (idãbobo) awọn iran Kuraeşi.

لِإِيلَٰفِ قُرَيۡشٍ ١

**2.** Ibasãba wọn lati mã rin ni akokò òtutu ati õrú.

إِۦلَٰفِهِمۡ رِحۡلَةَ ٱلشِّتَآءِ وَٱلصَّيۡفِ ٢